# IGBESI-AYÉ IWA-MIMỌ́

## 1 Peteru 1:1-25; 2:1-25.

## ẸKỌ 452 --- FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ẹ bọ̀wọ fun gbogbo enia. Ẹ fẹ awọn ará. Ẹ bẹru Ọlọrun. Ẹ bọ̀wọ fun ọba" (1 Peteru 2:17).**

### Iṣẹ ti a Rán si Wa

Peteru, Aposteli ni jẹ akikanju oniwaasu, o si ṣe iwaasu awọn ọrọ nla kan ti a kọ silẹ ninu Bibeli Mimọ́. Ninu awọn ori iwe wọnyii o n ṣapejuwe pẹlu nnkan miiran, igbesi-ayé iwa-mimọ́ Onigbagbọ. Peteru ti jẹ́ apẹja ri, oun si le ti mu diẹ ninu "koko ẹkọ" rẹ̀ lati inu iriri rẹ̀ atẹyinwa lo fun apejuwe.

A kọ́ ninu ẹkọ wa nipa ijiya Kristi nigba ti O wà ni ayé yii, pẹlu ogo ti o duro de ẹ lẹyin naa. Awọn Onigbagbọ ode oni ni iya lati là kọja, ṣugbọn ere ologo n duro de wọn bi wọn ba le foriti i de opin. Ṣugbọn awọn ohun kan wà ti wọn ni lati ṣe lati le jẹ́ aṣẹgun ni kikún.

### Igbesi-ayé Mimọ́

Nigba ti a ba rì igbala ati isọdimimọ a fẹran ọmọnikeji wa "gidigidi lati ọkàn wá", tabi pẹlu ifẹ gbigbona pupọ. Bi a bá fẹran ẹlomiran a kò ni ṣe ohunkohun lati pa wọ́n lara; a kò ni sọrọ ibi nipa wọn tabi si wọn; a ko ni fi ara wa si ipo ọla ṣaaju ẹlomiiran, a o si maa gbiyanju lati ran awọn eniyan lọwọ lati ri igbala. "Ki ẹnyin na si jẹ mimọ́ ninu iwa nyin gbogbo"; lai ṣe ani-ani itumọ eyi ni lati wà lai leeri, ni pipe ati mimọ́ ninu iwa wa ojoojumọ, ninu ọrọ ati ninu iṣe. A ni lati kiyesi ọrọ wa ki a má si ṣe sọrọ lile tabi kikoro si ẹlomiran.

Nigba ti Oluwa ba gba eniyan là kuro ninu ẹ̀ṣẹ, ohun ti o n ṣẹlẹ ni pe oun a fi arankan, ẹtàn, agabagebe, ilara, ati sisọ ọrọ buburu silẹ. Arankan ni ero "ki-tẹni-ma-dara" tabi ero buburu; itumọ ẹtàn ati eke fẹrẹ dọgba; agabagebe ni fifi ara wa hàn ni ẹni ti a ko jẹ; ilara ni jijowu oriire ẹlomiran. Lara sisọrọ buburu ni biba eniyan jẹ́, sisọrọ aitọ́ nipa rẹ̀, ati didoju ẹni kan kọ ẹlomiran. Pipurọ ati sisọrọ rirùn naa jẹ́ ọrọ buburu.

### Iyiiriwo ati Idanwo

Awọn eniyan ayé saaba maa n ka Onigbagbọ si ẹni ọtọ nitori wọn ki i huwa tabi ki wọn sọrọ bi awọn miiran, tabi ki wọn wọn aṣọ igbalode gẹgẹ bi iṣe awọn ẹlẹṣẹ. Ọrọ awọn ọdọ le maa koro pupọ, ki o si pa awọn ti n ṣe rere lara. Peteru wi pe ki ẹ maa yọ̀, bi o tilẹ ṣe pe 'fun igba diẹ, niwọnbi o ti yẹ, a ti fi ọ̀pọlọpọ idanwo bà nyin ninu jẹ". O ni idanwo ati iyiiriwo niye lori fun wa ju wura paapaa lọ, a si ni lati "yọ ayọ̀ ti a kò le fi ẹnu sọ, ti o si kun fun ogo". Eyi ko rọrun lati ṣe nigba ti wọn ba n fi wa ṣe ẹlẹya, tabi nigba ti a ba dá fasẹyin kuro ninu nnkan ti awọn ẹgbẹ́ wa n ṣe ni ile-ẹkọ, eyi ti awa mọ pe ko dara. Ṣugbọn bi a ba mu iduro wa, yoo sọ wa di akọni: yoo fun wa lagbara si i ninu Oluwa, yoo si fun wa ni oore-ọfẹ si i lati le la idanwo ti o le ju bẹẹ lọ kọja fun Jesu nigba ti o ba yẹ lati ṣe bẹẹ.

Awọn ẹlomiran ki i "dagba" nipa ti ẹmi, wọn a si maa jẹ ki idanwo wọn "dé wọn mọlẹ", wọn ro pe wahala wọn pọ̀ ju ti awọn ẹlomiran lọ.

### Ṣiṣakoso Ero Wa

Peteru wi pe ki "ẹ di ọkàn nyin li amure". Ni igba laelae awọn eniyan n wọ agbada gbariyẹ, pẹlu amure ni ẹgbẹ wọn. Nigba pupọ ni wọn n gbá isalẹ aṣọ wọn mu lati din in kù, ki o má ba di wọn lọwọ lati rin tabi lati sare, ṣugbọn ki wọn le wa ni imurasilẹ. A sọ fun wa lati "di" ọkàn wa "li amure" – ki a ṣe akoso ero wa, ki a gbé ọkàn wa le Jesu. Ki a ma ṣe fi ọkàn wa lé awọn nnkan ayé, ṣugbọn ki a ṣe aṣaro nipa Jesu ati ipadabọ Rẹ̀ kánkán. Paulu n kilọ fun wa lati maa gbero ohun wọnni ti i ṣe ọ̀wọ, titọ́, mimọ́, fifẹ́, ti o si ni iroyin rere.

**Igbesi-ayé Kukuru**

A ṣe apẹẹrẹ fun ni lati fi hàn bi Ọrọ Ọlọrun ti duro titi lae ati bi ọjọ ayé eniyan ti kuru pupọ to. "Gbogbo ẹran ara dabi koriko, ati gbogbo ogo rẹ bi itanná koriko. Koriko a mã gbẹ, itanná rẹ a si rẹ silẹ: Ṣugbọn ọ̀rọ Oluwa duro titi lai". Bi o ṣe ti awọn ipẹẹrẹ ọkunrin ati obinrin ti ẹrẹkẹ wọn n dán, ti wọn si kún fun okun ati ilera, o dabi ẹni pe wọn yoo wà bẹẹ pẹ́ titi, ní ero wọn. Ọpọ nnkan ni o wà lati ṣe; ọpọ ibi lati lọ; ọpọ igbadun ayé lati ni! Lootọ ni, paapaa fun awọn ti a ti gbala. Paapaa fun awọn ọdọ, ọpọ igbadun airotẹlẹ ni o wà layé. Awọn arugbo paapaa, ti n joko sinu aga irọrun, ti ko rọrun fun lati maa rin kiri, wọn ko gbagbe ayọ̀ igba ọdọ, wọn si n ṣe aṣaro igba ti o ti kọja lọ, ati eyi ti o n bọ̀. Sibẹ kukuru ni igba! Mose sọ ninu Orin Dafidi 90:10: pe "Adọrin ọdun ni iye ọjọ ọdun wa; bi o si ṣe pe nipa ti agbara, bi wọn ba to ọgọrin ọdun, agbara wọn lãla on ibinujẹ ni; nitori pe a ki o pẹ ke e kuro, awa a si fò lọ". Ọpọ eniyan lo maa n gbé ju aadọrin ọdun lọ layé, ṣugbọn bi wọn ti n dagba si i, ọpọ wọn ni aarẹ n mú, awọn ẹlomiran si ni lati ma ṣe itọju wọn.

Niwọn ọdun diẹ sẹyin awọn oṣiṣẹ Ile itọju alaisan lọ bẹ alagba ẹni ọ̀wọ̀ kan wo nibi akete aisan rẹ̀. O wi fun wọn pe nigba ti o ku diẹ ki aisan oun bẹrẹ, lowurọ ọjọ kan bi oun ti n ṣiṣẹ ninu abà ti a n kó ire oko si, ni ọmọbinrin ọmọ oun sare tọ oun wá pe, "Baba agba, a n ṣe ariya pe ẹ di ọgọrin ọdun lonii". Lojiji ni oun ri pe oun ti pé ọmọ ọgọrin ọdún. Oun ro o pe "Nibo ni gbogbo ọgọrin ọdún wọnyii lọ?" Ọjọ diẹ lẹyin naa ni o ṣaisàn, a si gbe e wá si ile itọju alaisan. Ibẹ ni o ti wá àyè lati wá Oluwa, a si gba a là. Ko pẹ lẹyin naa ni a pe e lọ si Ile rẹ̀ ọrun. Jesu Kristi "gẹgẹ bi ọ̀pọlọpọ ãnu rẹ̀" gba a ki o to pẹ́ jù. O dabi ẹni pe akoko n sare tete! A si n gbọ́ bi awọn agbalagba ti maa n sọ pe, "o dabi ẹni pe lana mo ṣi jẹ́ ọmọde".

Iku maa n mú awọn ọmọde ati ọdọ naa lọ nigba miiran, ko si si ẹni kan ninu wa ti o mọ ohun ti ọla yoo hù jade. Nisisiyii ni akoko lati wá Oluwa ki a si wà ni imurasilẹ lati pade Rẹ̀ ni alaafia.

**Jijiya Lai ṣẹ̀**

Peteru wi pe "nitori ọkàn rere si Ọlọrun" a ni lati ṣe tán lati jiya lai tọ́. Ko ṣanfaani fun wa lati "fesi" nigba ti a ba n ba wa wi fun aṣiṣe wa. Ṣugbọn bi a ba n ṣe rere ti a si bá wa wi le e , bi a ba fi suuru gba a, inu Ọlọrun yoo dùn si wa.

Gẹgẹ bi apẹẹrẹ, boya a sọ pe ki o ṣe nnkan kan o si ṣe eyi ti o ro pe o tọna ti o si ṣanfaani. Ṣugbọn boya ẹni kan ko fẹ, o si sọrọ lile si ọ. Bi o ba ni oore-ọfẹ Ọlọrun ninu ọkàn rẹ ti o si fi suuru gba a lai fesi, inu Ọlọrun yoo dùn si ọ Oun yoo si titori rẹ bukun fun ọ. Ọrọ naa le dùn ọ, ṣugbọn o ko fi i sọkan, o ko si ro ninu ọkàn rẹ pe: Nn o san án pada fun ọ". Nigba naa ẹri-ọkàn rẹ mọ́ niwaju Ọlọrun ati eniyan. O si le gbadura fun oluwarẹ.

**Kristi Apẹẹrẹ Wa**

"Kristi pẹlu jiya fun nyin, o fi apẹrẹ silẹ fun nyin, ki ẹnyin ki o le mã tọ̀ ipasẹ rẹ̀: ẹniti kò dẹṣẹ̀, bẽni a kò si ri arekereke li ẹnu rẹ̀: ẹni, nigbati a kẹgan rẹ̀, ti kò si pada kẹgan; nigbati o jiya, ti kò si kilọ." Ninu wa ko si ẹni ti o ti i jiya ri bi Oun ti jiya; a ko le mọ bi agbelebu ti O rù fun wa ti wuwo to; a ko si le san an pada fun Un lae, ani niwọn kinun. Eyi ti o kere ju lọ ti a le ṣe ni lati gbé agbelebu wa, ki a tẹle E timọtimọ ki a si mura lati jiya lai tọ́ fun orukọ Rẹ̀.

Ọpọ awọn ẹlẹri eke lo tako Jesu ṣugbọn Oun ko sọrọ. Wọn tutọ si I loju wọn si fi ọwọ wọn lu U. Wọn bọ́ aṣọ Rẹ̀ a si fi aṣọ elese aluko wọ Ọ. Adé ẹgun ti a fi ẹgun titobi ti o si mú ṣe ni a gbé ka ori Rẹ̀. Wọn fi ọpa iye si ọwọ Rẹ̀ wọn si kunlẹ niwaju Rẹ̀ wọn si fi I ṣe ẹlẹya. A mu ki o ru agbelebu Rẹ̀ funra Rẹ̀; a kan An mọ́ agbelegbu a si fun Un ni ọti kikan ti a ti po mọ orooro lati mu.

"Ẹniti on tikararẹ̀ fi ara rẹ̀ rù ẹ̀ṣẹ wa lori igi, pe ki awa ki o le di okú si ẹṣẹ ki a si di ãye si ododo: nipa inà ẹniti a mu nyin larada". Nitori ti wa ni: lati mú ẹ̀ṣẹ wa kuro, lati sọ wa di mimọ́ ati lati wo wa sàn.

**Oluṣọ-agutan ati Agutan**

Lai ṣe aniani gbogbo yin lo ti ri aworan agutan kekere ti o sọnu ti o ṣubu si ẹba oke. Oluṣọ-agutan alaanu yii, ti a fi hàn bi Jesu pẹlu ade ẹgun lori, lọ sibẹ o si yọ agutan kekere naa. Jesu ni, "Ẹnyin ti rò o si? Bi ọkunrin kan ba ni ọgọrun aguntan, bi ọkan nù ninu wọn, ki yio fi mọkandinlọgọrun iyokù silẹ, ki yio lọ sori òke lọ iwá eyi ti o nù bi?" (Matteu 18:12). Ki ni idahun rẹ si ibeere yii?

Ki a to gbá wa la, a "ti nṣako lọ bi agutan, ṣugbọn nisisiyi ẹnyin pada si ọdọ Oluṣọ-agutan ati Biṣọpu" ọkàn wa. Ẹ má ṣe jẹ ki a ṣina kuro lọdọ Jesu, Oluṣọ-agutan Rere.

**AWỌN IBEERE**

1. Iyì wo ni a fi sori "idanwò igbagbọ́ nyin"?
2. Ki ni itumọ "ẹ di ọkàn nyin li amure"?
3. Ki ni ṣe ti a fi ni lati jẹ mimọ́?
4. Ki ni itumọ "gbogbo ẹran-ara dabi koriko"?
5. Ọrọ Oluwa yoo ti duro pẹ to?
6. Ki ni a sọ fun wa lati fi lelẹ ni apá kan?
7. Ki ni ṣe ti a fi n digba pe awọn Onigbagbọ́ ni eniyan ọ̀tọ?
8. Bawo ni awọn ọmọ-ọdọ ṣe ni lati ṣe si oluwa wọn?
9. Sọ bi Kristi ṣe di apẹẹrẹ pipé fun wa.
10. Iru ifiwera wo ni a ṣe laaarin eniyan ati agutan?